**ORÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́ ÌYANU**
Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nigeria.
**ÈTÒ ÌPÀDÉ AGBÁRA GBỌ́DỌ̀ PÀRỌ̀ ỌWỌ́**

**ÌTUSÍLẸ̀ TO JÌNLẸ̀ (1)**
**OṢÙ KẸRIN, ỌDÚN 2024**
Ìwé Mímọ́ kíkà: Márkù 9
Ìjẹ́wọ́: Lúkù 4:18

## ORIN ÌYÌN ÀTI ÌJỌ́SÌN TÍ Ó L'ÁGBÁRA

1. Ọlọ́run, dìde, kí Ó sì fàtu ohunkóhun tí O kò gbìn sínú Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìṣọ́ji, bà lé Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
3. Ọlọ́run, jẹ́ kí agbára àláfíà àti itẹ̀síwájú, ṣíji bo orílẹ̀-èdè yìí, ní orúkọ Jésù.
4. Ọlọ́run, dìde, kí O sì fún wa ní àwọn olórí tó bẹ̀rù Ọlọ́run, ní orúkọ Jésù.
5. Ìwọ agbára ìwòsàn àti ìtúsílẹ̀, bàlé mi báyìí, ní orúkọ Jésù.
6. Gbogbo ègún àìsàn àti àìlèra ìrandíran nínú ayé mi, fọ́ nípa agbára tó mbẹ nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù, ní orúkọ Jésù.
7. Ọlọ́run dìde, jẹ́ kí gbogbo iṣòro olóríkunkun ìrandíran nínú ayé mi kú, ní orúkọ Jésù.
8. Gbogbo òbìrí ìnira ìrandíran, fọ́ , ní orúkọ Jésù.
9. Gbogbo gúnugún ayànmọ́ ilé bàbá mi, kú, ní orúkọ Jésù.
10. Iná Ẹ̀mí Mímọ́, fọ ẹ̀jẹ̀ mí mọ́ kúrò nínú àjogúnbá ibi, ní orúkọ Jésù.
11. Mo fọ́ gbogbo àlá òṣì mọ́lẹ̀, ní orúkọ Jésù.
12. Gbogbo agbára búburú láti ilé bàbá mi, kú, ní orúkọ Jésù.
13. Agbára Ọlọ́run, fá àwọn irúgbìn ìkà tu u kúrò nínú ayé mi, ní orúkọ Jésù.

14. Gbogbo agbára tí wọ́n yàn láti ba ayé mi jẹ́, túká, ní orúkọ Jésù.
15. Gbogbo agbára búburú ilé bàbá mi tí kò fẹ́ jẹ́ kí n lọ, kú, ní orúkọ Jésù.
16. Gbogbo igi àjẹ́ tí ó de olubi mi, kú, ní orúkọ Jésù.
17. Gbogbo ẹ̀jẹ̀ tó n sọ̀rọ̀ lòdì sí ìrandíran mi, gba ìpalẹ́numọ́ nípa ẹ̀jẹ̀ Jésù.
18. Mo fọ́ gbogbo májẹ̀mú ìrandíran pẹ̀lú àwọn agbára búburú ilé bàbá mi, ní orúkọ Jésù.
19. Ìdókòwò sátánì nínú ìpìlẹ̀ ayé mi, kú, ní orúkọ Jésù.
20. Májèlé ìgbà èwè tó farasin, tó n kó àdàlù bá ayé mi, gba iná, ní orúkọ Jésù.
21. Gbogbo ipá tó lòdì sí ìràwọ̀ ìdílé mi, kú, ní orúkọ Jésù.
22. Mo gba òmìnira kúrò nínú àwọn àlá àìbalẹ̀ ọkàn sátánì, ní orúkọ Jésù.
23. Ìràwọ̀ mi, gbóná jù fún ọ̀tá láti gbámú, ní orúkọ Jésù.
24. Olúwa, jẹ́ kí a fún èémí jade kúrò nínú àwọn tó n fi àlá gbógun tì mí, ní orúkọ Jésù.
25. Mo dè, mo sì yàlárọ gbogbo ọkùnrin alágbára ikú àti ipò òkú, ní orúkọ Jésù.
26. Mo tú ara mi sílẹ̀ kúrò lọ́wọ́ ìgbámú ọkùnrin alágbára ìbálópọ̀ ìyówù, ní orúkọ Jésù.
27. Agbára tí kì í jẹ́ kí ènìyàn ní ìtẹjúmọ́, tó n yọ ayànmọ́ mi lẹ́nu, kú, ní orúkọ Jésù.
28. Gbogbo àwọn ọpọ̀lọpọ̀ ọkùnrin alágbára tí wọ́n n ṣiṣẹ́ lòdì sí ayànmọ́ mi, ẹ yarọ, ní orúkọ Jésù.
29. Ìwọ ọkùnrin alágbára tó n ṣe ìparun fún ara àti èrò inú, já ìdè rẹ lórí ayé mi, ṣubú lulẹ̀ kú, ní orúkọ Jésù.
30. Mo gbédè, mo sì yàlárọ gbogbo ọkùnrin alágbára ikú àti ipò òkú, ní orúkọ Jésù.
31. Mo tú owó mi sílẹ̀ kúrò nínú ilé ọkùnrin alágbára, ní orúkọ Jésù.
32. Mo jó ojúbọ ọkùnrin alágbára nínú ìdílé mi run nípa iná Ọlọ́run, ní orúkọ Jésù.

33. Gbogbo àlúfà sátánì tó n ṣiṣẹ́ ìránṣẹ́ nínú ìran ìdílé mi, ṣí wọ́ iṣẹ́, ní orúkọ Jésù.
34. Àwọn ọfà àìsàn tí wọ́n jẹyọ láti ipaṣẹ̀ ìbọ̀rìṣà, já ìdè rẹ, ní orúkọ Jésù.
35. Gbogbo àsopọ̀ àwọn agbára búburú ilé bàbá mi, láti ìlú abínibí mi, tó n mú iṣòro wọnú ayé mi, túká, ní orúkọ Jésù.
36. Gbogob ìfinijì sátánì tó n sọ̀rọ̀ lòdì sí mi, túká nípa agbára tó mbẹ nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù, ní orúkọ Jésù.
37. Gbogbo pẹpẹ ibi àtinúwá tí n kò mọ̀ nípa rẹ̀, yangbẹ, ní orúkọ Jésù.
38. Ohùn àwọn agbára ibi ìrandíran ti ilé bàbá mi kò tún ní sọ̀rọ̀ mọ́, ní orúkọ Jésù.
39. Gbogbo ìwé àdéhùn sátánì tí àwọn bàbá nlá mí kọ nípa mi, gba ìfagilé, ní orúkọ Jésù.
40. Aṣọ àtakò tí àwọn agbára búburú ilé bàbá mi rán fún mi, yangbẹ, ní orúkọ Jésù.